# Àgbéjáde Àwọn Ẹ̀tọ́ Ọmọ Ènìyàn ni Káàkiri Àgbáyé

In commemoration of the *Fiftieth Anniversary of the Universal Declaration of Human Rights (1948-1998)*

# Agbéjáde Awon
# Ẹ̀tọ́ Ọmọ Ènìyàn
# ní Kaakiri Àgbáyé

A TRANSLATION OF THE
UNIVERSAL DECLARATION
OF HUMAN RIGHTS

*Into*

# YORÙBÁ

Bęęsini a tún mo pe àìbòwò fún ètó omo èniyàn maa n fa àwon ìwà tí kò bójú mu eyi tó lòdí si èrí-okàn Ọmọ èniyàn, ati ìgbé ninu ayé ti gbogbo Ọmọ - ẹda ti le maa jola ìgbádùn òminira ọrọ sísọ ati nínì ìgbàgbó lori ohun ti èniyàn bá fé ati ominira lati ni ìgboyà ati lati maşe aláìní jẹ ohun to awọn eniyan n lepa.

Bẹẹ ni a mò pe o se kókó wipe tí kò ba ṣe pe wọn sun eniyan kan ògiri lati tako ìfìyà jẹ́ni ati ifi imu eni se tópolá, ìlàna ofin gbodo daabóbò ètó omo èniyàn.

Bee ni a mo wipe o se kókó lati mu igbèèrú bá ìdàgbàsókè, ìrépò laarin awon orílè-èdè.

Bẹẹ ni a mo wipe awon èniyàn Àjo Ìsokan Agbáyé ti pinnu labe ofin wipe awon ni ìgbàgbó ninu ìpìlè ètó Omo èniyàn ati ètó dogba - n - dogba fun awon Okùnrin ati Obìnrin pèlú pípinnu lati jeki ìdàgbàsókè àwùjo olómìnira wà pèlú ìgbé ayé to péye fun awon eniyan lápapò.

## ÀGBÉJÁDẸ À WON ÈTÓ OMO ÈNÌYÀN NÍ KAAKIRI ÀGBÁYÉ

Ni ọjọ Kẹ́wà oṣù Kéjìlá odun 1948, ìpàdé àpápọ̀ Ajo Ìsòkan Àgbáyé fohùn sòkan lori àgbéjáde awọn ẹ̀tọ́ Ọmọ ènìyàn ní àgbáyé. Àtúpalè re ni ó wà ni àtèlé àwon ojú ewé ìwé yi. Léhìn àgbéjáde ohun itan yi. Ajo naa wa kesi gbogbo awọn orílè-èdè ti won je Omo egbé lati Polongo agbejade yi, ni àwon ilé - ìwé ati awon ibùdó ikékò ti yo fi lè da duro labe ètò ìsèlú orílè - èdè kọ̀ọkan.

## ÌKÉDE AGBEJADE AWON ÈTÓ OMO ENIYAN NI KAAKIRI ÀGBÁYÉ

## ÌFÁÁRÀ

Bẹ́ẹ̀sini a gbọ pé èto ti kò ni àbàwón tí kò sì fi síbì kan to wa fun gbogbo Omo èdá je gbòngbò Òmìnira, ìdájó ati àlááfíà lagbaye,

Bee si ni awon Omo egbe ti jẹjẹ lati se ìkósejári awon ipinnu yi ni ìfowósowópò pèlú Ajọ-Ìsòkan Àgbáyé, mimu ìgbèèrú bá ibòwò fún ètó Omo ènìyàn lábé ìlànà Olómìnira.

Béé ni a mò wipe nini àgbóyé àwon ètó ati òmìnira wonyí se pàtàkì púpò fun ìyege àwon èjé yi.

Nitorina, ÌPÀDÉ AJỌ APÁPỌ̀ FỌWỌ́ SII Pẹ́
ÀWỌN ẸTỌ́ ỌMỌ ÈNÌYÀN NÌWÒNYÍ

Gẹgẹ bi aṣeyọri kanna fún gbogbo awọn ènìyàn ati àwon orílè-èdè ẹni kọọkan, ẹgbẹ ati òtòkùlú láwùjo mú oro àgbéjáde yi lókùndùn pèlu iyanu lati koni ati lati toni sóna fún ìgbèrú awon ètó wonyi ati ominira alájosepò lórílè-ede ati lagbayé fun mímo rírì re láwùjo laarin awon orílè-èdè to jẹ Ọmọ ẹgbẹ ati awon agbègbè tó wà lábé àkóso won.

## ÌSỌRÍ KINI

Gbogbo Omo-eda ni a bi pèlú ominira ati ẹtọ dogba-n-dogba. Wọn ni òòye ati èrí-okàn, wọ́n si gbodo maa hùwà si omonikeji pèlú èmí ìsòkan.

## ÌSỌRÌ KEJÌ

Gbogbo eniyan lo ni ètó ati ominira to wa ninu ikéde yi lai ya ohunkohun sọ́tọ̀ bii ẹ̀yà àwọ̀ ara ẹni, bóyá eniyan je Ọkùnrin tàbí Obìnrin èdè, ẹ̀sìn, ọ̀rọ̀ ìsèlú tàbi awon ipinnu míràn, lorile-èdè abínibí eni, dúkìa, bíbíre tabi awon ohun miran.

Siwaju si, kò gbodo sí ìyasọ́tọ̀ lori ọ̀rọ̀ ìsèlú, ipò orílè-èdè kan si ikeji lágbaye ti enikeni le jẹ Ọmọ bibi ibè, yálà o je orílè-èdè olómìnira tabi bẹ́ẹ̀ kọ, tabi labẹ ohun yowu tó lè tẹ ẹ̀tó rè lójú.

## ÌSỌRÌ KẸTA

Gbogbo ènìyàn lo ní ètó sí ìgbé ayé ominira ati ìdáabòbò.

## ÌSỌRÌ KẸRIN

A kò gbódò mu ẹnikẹ́ni ni ẹrú tabi kàn-àn nípá fún ẹnikẹ́ni lati síngbà, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni òwò erú jẹ èèwọ̀ ni gbogbo ọ̀nà.

## ÌSỌRÍ KARÙN

A kò gbọdọ fi iyà jẹ ẹnikẹni tàbí ìkórira-ẹni bíi ìhùwàsí ti ẹranko, tabi fi eniyan si ìpò àìbẹ́gbẹ́ pe, tabi si ipo ìfiyàjẹni.

## ÌSỌRÍ KẸFÀ

Gbogbo eniyan lo ní ẹ̀tọ́ si ikani kún gẹgẹ bi ẹ̀dá aláàyè labẹ́ òfin.

## ÌSỌRÍ KEJE

Gbogbo èniyàn lo dọ́gba labẹ́ òfin ti won sì ní ẹ̀tọ́ ààbò labẹ́ òfin láìsí ètanú. Gbogbo wọn lō sì ní ẹ̀tọ́ ààbò ni dogba-n-dogba lori ìkórira tí ó lódi si eniyan lori ẹ̀tọ́ si ìdáàbòbò dọgba-n-dọgba.

## ÌSỌRÍ KẸJỌ

Gbogbo eniyan lo ni ẹ̀tọ́ si ìgbanilà labẹ ìgbìmọ alágbòròdùn to n daa-bobo awon ìlàna tó lè tàpá si awon òfin tó ba jẹ àtakò sì ẹ̀tọ́ ẹni gẹgẹ bi o ti wà ninu ẹ̀tọ́ iṣelu ati àkọsílẹ̀ òfin

## ÌSỌRÍ KẸSAN

A kò gbọdọ fi ipá mú ẹnikẹni láì nidi tabi ifini si àhamọ tabi ìleni kúrò ni orílẹ̀-èdè ẹni.

## ÌSỌRÍ KẸWA

Gbogbo eniyan lọ ní ẹ̀tọ́ ni dọgba-n-dogba si ìgbẹ́jọ́ àìfisíbìkan niwajú ìgbìmọ̀ awọn olùgbẹ́jọ́ lori ìràpadà awon ẹ̀tọ́ ati ojúṣe ẹni naa fun ẹsùn ìwà ọ̀daràn ti won lè fi kàn-án.

## ÌSỌRÍ KỌKÀNLÁ

Gbogbo eni to won ba pè lẹ́jọ́ ìwa ọ̀daràn ni ó ni ẹ̀tọ́ pé kò mọwọ́-mẹsẹ̀ lori ẹsun ọ̀daràn naa titi ti ofin yo fi fídí ọ̀ràn naa mulẹ̀ pe ó jẹbi nibi ìgbẹ́jọ́ ojítayé eyi ti oní tọ̀ún gbọdọ ni gbogbo awọn ohun to yẹ fún idáabòbò lati wi àwíjàre bii agbẹjọ́rò.

Kò si ẹnikẹni ti a gbọ́dọ̀ sọ wipe o jẹbi ìwà ọ̀daràn nigba ti irú ìwà bẹ́ẹ̀ kii se iwà ọ̀daràn lásìkò ti onítọ̀ún hùwà yi. Bẹ́ẹ̀ni ìjìyà kò gbọdọ́ pọ̀jù tayọ bi o ti wà ní àkọsílẹ̀ ofin ti o rú yi.

## ÌSÒRÍ KEJÌLÁ

Kò sí ẹnikẹ́ni tí a gbọ́dọ̀ kọlu kọlọfin rẹ̀, ẹbí, ilé tabí ìwé tí wọn kọ sí onítòún tabí àtakò sí owó ati ọla rẹ̀.

Gbogbo eniyan loni eto idaabobo lati koju awon atako yi

## ÌSỌ̀RÍ KETÀLÁ

1. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ sí òmìnira yíyan fanda ati gbigbe ni aaye ibùgbé ni ààlà orílẹ̀-èdè rẹ.

2. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ lati fi orílẹ̀-èdè rẹ̀ sílẹ̀ ati lati pádà ti o ba wùú.

## ÌSỌ̀RÍ KẸRINLA

1. Gbogbo ènìyàn loni ẹ̀tọ́ lati bèèrè ati lati jọlá ìdáàbòbò ni orílẹ̀-èdè miran bi a ba wà ninu ipò ìfipá jẹ gàba lori ẹni lórílẹ̀-èdè tírẹ̀.

2. Wọn lè fagile ẹ̀tọ́ yi ti àridajú bá wà pe iru ẹni bẹẹ jẹ̀bi ẹ̀sùn ìwà ọ̀daràn yàtò fun ti òṣèlú tabi awon ìlànà ààbò ti Ajọ Isọ̀kan Àgbáyé ya sílẹ̀ fun ẹtọ ẹni kọ̀ọ̀kan.

## ÌSỌRÍ KẸẸ̀DÓGÚN

1. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ ati je Ọmọ oríìè-èdè kan.

2. Kosi ẹnikẹni ti a gbọ́dọ̀ tako jíjẹ́ omo orílẹ̀-èdè rẹ, tabi ki a ta kòó ti o bá fẹ́ jẹ Ọmọ orílẹ̀-èdè miran.

## ÌSỌRÍ KẸRÌNDÍNLÓGÚN

1. Tọkùnrin, tobìnrin to ba ti bàlágà loni eto lati ni ìyàwó tabi ọkọ kí wọn si ko ẹbí jọ. Wọn ni ẹ̀tọ́ dọgba-n-dọgba lori ìgbéyàwó ati ìlọ́kọ ati lásìkò àbágbépọ̀ wọn tabi ti won ba túká.

2. Ìdàpọ̀ tokùnrin-tobìnrin gbọ́dọ̀ waye ni tọkan-tọkan pẹ̀lú ìfẹ́ ọkan awọn ti wọn ba fẹ fẹra won, láì fipa mu wọn.

3. Ẹbí jẹ gbòǹgbò àwùjọ, wọn si ní ètó ìdáàbòbò lọwọ àwùjọ ati ìjọba.

## ÌSỌRÍ KẸTÀDÍNLÓGÚN

1. Gbogbo eniyan loni ètó lati ni dúkìá l'oun nikan ṣoṣo tabi ni ajọnípọ̀ pẹlu awọn ẹlòmíràn.

2. A kò gbọdọ̀ fi ipá gba dúkìá ẹnikẹni

## ÌSỌRÍ KEJÌDÍNLÓGÚN

Gbogbo ènìyàn loni ẹ̀tọ́ si ominira èrò, èrí-okàn ati èsìn, lara ẹ̀tọ́ yi ni ominira lati yi èsìn tabi ìgbàgbọ́ eni padà fúnra ẹni tabi pẹlu àwùjo ni ìkòkò tabi ni gbangba lati fi èsìn náà jọ́sìn, kọ́ni tabi polongo rẹ̀.

## ÌSỌRÍ KỌKÀNDÍNLÓGÚN

Gbogbo ẹniyan loni ẹ̀tọ́ ominira lori èròǹgbà ati àsọjáde, lara ẹto yi ni ominira lati pinnu láìsí ìyojúsí, ati lati béèrè, gbà tabi tani lólobọ́ lori èrò okàn ninu àgbéjáde oríyìn yówù nípasẹ̀ ilé-iṣẹ́ Ìròyìn.

## ÌSỌRÍ OGÚN

1. Gbogbo eniyan loni ètó òminira àpèjọ àláàfíà ati jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́.
2. A kò lè kàn-án nipa fun ẹnikẹni lati darapọ̀ mọ́ ẹgbẹ kan.

## ÌSÒRÍ KỌKÀNLÉLÓGÚN

1. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ lati lówó ninu ìjoba orílẹ̀-èdè re, yálà ni ìdáduró tabi nípasè asọjú tí a yàn funra ẹni.

2. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ dogba-n-dogba lati kopa ninu ṣiṣẹ isé ilú orilẹ-ẹdẹ rẹ.

3. Ohun ti awon eniyan ba n fe ni yó je ìpìlẹ̀ ase ijoba eyi ti yo maa wayé nílarè-ìlàrè ati eto idibo alailabawon fun gbogbo gboo ni dogba-n-dogba ti won gbodo di ni koko tabi eto idibo to ja gaara.

## ISORI KEJILELOGUN

Gbogbo eniyan loni eto si idaabobo lawujo nipase akitiyan ijoba orile-ede ati ìfowósowópò orile-èdè sórílè-èdè, lori ìwòn ba ohun àlùmónì ìpínlẹ̀ kòòkan, ẹtọ nipa ti àsà ati ninu ìdàgbàsókè bá ara ẹni.

## ÌSỌRÍ KẸTÀLÉLÓGÚN

1. Gbogbo eniyan loni ẹ̀tọ́ lati ṣiṣẹ́, òmìnira iṣẹ́ tó wuni ati Ìbojútóní lẹ́nu isé pelu ìdáàbòbò lowo àìrísése.

2. Gbogbo eniyan loni ètó si ìgbowó osù kanna, lori isé, kanna.

3. Gbogbo eni to ba ńsisé loni ètó si owó isé tó jojú eyi to fi léè gbe ìgbé aye Omolúàbí

4. Gbogbo eniyan loni ètó lati dá egbé awon òsìsé sile tabi lati darapò mo egbé tó bá lè dáàbòbò ẹ̀tọ́ rẹ.

## ÌSỌRÍ KẸRÌNLÉLÓGÚN

Gbogbo eniyan loni ètó isinmi ati ìnajú, pelu àsìkò ise ti ko gbodo dánilágara ati aaye isimi ni ilàrè - ìlàrè pẹlu sisan owó fun-un

## ÌSỌRÍ KẸ́ẸDỌ́GBÒN

1. Gbogbo eniyan loni èto si ìgbé ayé rere to ye Omolúàbí ati èto ilera fun òun ati ebí

rẹ, pẹ̀lú ounjẹ, aṣọ wíwò, ilé-gbígbé eto ìwòsàn ati pípèsè awon ohun amuludun pelu eto ìdáàbòbò lọ́wọ́ àjálù ainíse lọ́wọ́ àìsàn, àidápé-lara, opó, ogbó tabi awon ohun miran to koja agbara rè.

2. Àwon abiyamo ati Omo kékèké ni eto si àkànse àbojútó ati ìrànlọ́wọ́. Gbogbo Omo, yálà won bíi lónà ètó labé ìgbeyàwó ni, tabi síta lo ni ẹtọ lati jolá ìdáàbòbò àwùjo.

## ÌSÒRÍ KERÌNDÍNLÓGBÒN

1. Gbogbo eniyan loni ètó si imo èkó ìwé Èkó si gbódò je òfé o kéré tan fun alakobérè ati jélé-o-sinmi. Èkó alákobérè gbódò je dandan. Èkósé-owó ati ti ìmò gbógbò -n -se gbódò wa ni àrowótó pelu ètò ilé èkó gíga, gbódò wà fun gbogbo gbòò lori ìdúró enìkòòkan.

2. Ètò èkó maa wà fún mímú ìdàgbàsókè bá Omo - èdá ati nini agboye ati ìbòwò fún ètó ati òmìnira eni. Yoo mu ìgbèrú ba àgbóra-

ẹni ye, ajọse, ifarada ati ife laarin gbogbo orilẹ-ede, ẹya, tabi ẹsin fun ilọsiwaju akitiyan. Ajo Isokan Agbaye ati ifesẹmulẹ alaafia.

## ÌSÒRÍ KETADÍNLÓGBÒN

1. Gbogbo eniyan loni eto lati kopa ninu àsà àwùjọ rẹ, ki o fi lè je ànfààní ìtèsíwaju ninu ìmọ̀ ijìnlẹ̀.

2. Gbobo eniyan loni ẹtọ́ ìdáàbòbò lori gbogbo ohun kohun to ba fi opolo rẹ̀ gbéyọ

## ÌSÒRÍ KEJÌDÍNLÓGBÒN

Gbogbo ènìyàn loni ẹtọ́ si ìlànà awujọ ati ti orílẹ̀-èdè si rílẹ̀-èdè lagbye ninu eyi ti gbogbo awọn eto ati ominira to wà ninu ikede yi yo ti di mimuse.

## ÌSÒRÍ KOKÀDÍNLÓGBÒN

1. Gbogbo eniyan loni ojúṣe si àwujọ nibi ti ìdàgbàsókè ti lè ba oníṭọ̀ún.

2. Nipa ìlàkàkà lati je ìgbàdùn ètó ati ominira wonyi, ènìyàn gbódò tèlé ìlànà òfin to da lori ìdaàbòbò fun àwùjo, àlàáfià ati àbójútó ilú nibi ti ètò ijoba tiwa-n-tiwa bá wà.

3. A ko gbodo lo awon ètó ati ominira wònyí lónà to tako ilana ati ipinnu Ajo - Isokan Àgbáyé ipinnu yi.

## ÌSÒRÍ OGBON

Kò sí ohunkohun ninu ikede yi ti a gbódò, tumo si wipe ijoba kan, ìkò egbe tabi enikan ni ètó lati se ohun-kohun kan tabi lati sakitiyan to lè gbégi lé èyikéyi ninu awon ètó ati ominira ti a là sílè wònyí.